ILANA ISE SAA KETA (SSS 1)

| OSE | AKOONU ISE |
|---|---|
| Kin-in-ni: | Oge sise nile Yoruba: Ohun ti oge sise je, awon ona ti Yoruba n gba soge: aso wiwo, irun didi, Irun gige / fifa, laali lile, osun kikun, tiroo lile ati bee bee lo. |
| Keji: | Isori oro ( oro-aropo-oruko, oro-aropo-afarajoruko): Alaye lori oro-aropo-oruko ati oro-aropo-afarajoruko ati bi a ti n lo won ninu gbolohun. |
| Keta: | Isori oro ( oro-ise): Alaye lori oro-ise, bi a ti n lo won ninu gbolohun ati awon orisii oro-ise |
| Kerin: | Asa isomoloruko nile Yoruba: Ohun ti isomoloruko je, awon ojo ti a n somo loruko nile Yoruba, awon ohun elo isomoloruko ati bi a ti n lo won. |
| Karun-un: | Iwe litireso kika: Kika iwe ‘ Nitori Owo’ |
| Kefa: | Idanwo ilaji saa / Itupale gbolohun oniponna: Ohun ti gbolohun oniponna je, awon itumo ti gbolohun oniponna le ni |
| Keje: | Asa isinku nile Yoruba: Ohun ti isinku je, orisii oku, oku abami, awon igbese sisin oku agba |
| Kejo: | Eka-ede ati Yoruba ajumolo : Ohun ti eka-ede je, awon orisii eka-ede ati oro ninu won / Aroko ajemo-isipaya: Alaye lori aroko ajemo-isipaya, awon ori-oro aroko ajemo-isipaya ati kiko Aroko ajemo-isipaya |
| Kesan-an: | Ere idaraya nile Yoruba laye atijo ati lode oni : Ohun ti ere idaraya je, alaye lori awon ere idaraya aye atijo bii okoto tita, boju boju ati bee bee lo ati ere idaraya ode oni bii ludo tita, ayo tita ati bee bee lo. |
| Kewaa: | Owo yiya ati ona igbagbese: Ohun ti owo yiya je ati awon idi ti a fi n yawo, awon ona ti a n gba lati gba gbese lowo awon ti ko fe san owo ti won ya |
| Kokanla: | Atunyewo ise saa |
| Kejila: | Idanwo ipari saa |

# OSE KIN-IN-NI

## OGE SISE NILE YORUBA

Oge sise je ona ti a n gba se faari ti eeyan yoo fi dun un wo. Tokunrin tobinrin lo n soge lawujo Yoruba. Eni to ba moge se, to gbo faari ti kii rin idoti ni Yoruba n pe ni Afinju. Eni ti ko gbo faari, ti ko mara mu to tun je onidoti ni a n pe ni Obun. Yoruba maan so wi pe:

Afinju woja, won a rin gbendeke,

Obun woja, won a pa siosio,

Obun siosio ni yoo reru Afinju rele.

Pataki oge sise ni wi pe ' Ba a se rin laa koni' ati wi pe 'Irinisi ni isoni lojo'.

### AWON ONA TI A N GBA SE OGE

1. Aso wiwo: Oun ni olori oge sise. O n je ki a mo iyato laaarin afinju ati obun. Aso to mo ti won lo daadaa ni Yoruba n wo soge. A le paso ni aro tabi di won ni adire, lona ti yoo fi ewa kun aso naa.
    a. Aso okunrin: Won wo ewu awotele bii buba , ewu awoleke bii dandogo, sapara, gbariye ati agbada. Won n wo sokoto bii sooro ati sokoto elenu gbanu fi soge. Won n de fila bii gobi, tinko,abeti-aja ati fila katiko si imura won.
    b. Aso obinrin: Won n wo buba, iro ati gele. Gele nla ni awon abileko n we ti awon olomoge si n we gele kekere. Awon abileko le gbe iborun le ejika apa osi tabi ki won gbe ipele le ori aso iro.
2. Irun didi: Awon obinrin lo n dirun lawujo Yoruba, o si n mu ki won rewa sii. Orisiirisii sitai irun ti won n di ni: kolese, ipako elede, suku, kojusoko, panumo, ojo-ma-peti, koroba ati bee bee lo.
3. Irun fifa : Awon agbalagba okunrin lo n fa irun kodoro ti yoo maa dan kogba. Awon adosu orisa ati awon emese oba naa maa n fa ori apa kan da apa kan si tabi da osu si ori. Irun fifa yii maa n bu kun ewa won.
4. Irun gige: Awon okunrin lo n gerun laye atijo, o si maa n je ki won rewa loju. Awon onigbajamo ni won n fi irun gige se ise laye atijo.
5. Ara finfin: O je ona ti awon alabe n gba fi kun ewa ara eeyan. Awon omoge lo maa n fin apa, yaju, ikun ati ese.
6. Eyin pipa: Eyin oke ni iwaju ni awon Yoruba maa n pa, lati fi alafo kekere sii. Alafo yii ni a mo si eji. O n je ki eeyan dun un wo.

7. Tiroo lile: Awon obinrin ati awon agbalagba okunrin lo maa n le tiroo laye atijo, lati mu ki oju gun rege ki o si dun un wo. Awon odomokunrin to n waya naa maa n le tiroo. O maa n je ki oju rewa.
8. Laali lile: Awon obinrin lo maa n le laali sowo ati atelese won. Awon olomoge to n lo ile oko naa maa n le laali. Oroo laali lo n je ki ibi ti won le e si pa awo da di pupa.
9. Osun kikun: Awon obinrin lo maa n fi osun para leyin ti won ba we tan. O n je ki awo ara yo. Awon abiyamo naa fi n pa omo ikoko lara. Won maa n wi pe 'Kii tan nigba osun ka ma ri fi pomo lara'.
10. Ila kiko: O je ona isaraloge lawujo Yoruba. O maa n bu ewa kun oju. Lara ila ti Yoruba n ko ni: Ila ondo, Pele,Abaja, Baamu, Keke, Ture ati Gombo.
11. Lilo egba : Awon obinrin lo maa n lo orisiirisii eso ara bii egba orun, gbede orun, egba owo, oruka, ifunpa, ifunse, yeti seti ati bee bee lo. Won tun lo orisiirisii ileke si orun ati idi lati soge. Lara ileke ti won n lo ni iyun ati lagidigba.
12. Opa itile: Awon agbalagba okunrin lo n lo opa itile paapaa ti won ba n lo sode. Won maa n se opa losoo lona ti yoo mu un dun un wo.

## ISE SISE

Fi oge sise laye atijo we tode oni. Bi apeere, laye atijo obinrin nikan lo n wo yeti sugbon lode oni, awon okunrin ti n wo yeti lati fi soge. Awon okunrin kan n wo eti kan soso nigba ti awon miiran n wo eti meji.